# Itore-Aanu, Adura Ati Awe Nigba Gbogbo Ko Tii To

Revd. Edward Omojevbe Eruteya

Ever-Flowing Grace Assembly

nipa adura ati itore-aanu ti Korneliu n se; Adura re ati ore aanu ti goke lo iwaju Olorun fun iranti (ese 4); Kii se pe awon nnkan yii ti fun un ni igbala. Ti o ba je pe won ti fun un ni igbala ni, ko tun nilo lati gbo ohun ti o gbodo se lati enu Simoni Peteru (ese 6). Ohun ti o dara ni. Korneliu ati awon ara ile re ko fi owo yepere mu adura igba gbogbo pelu awe ati itore aanu. Sibesibe ninu eeto Olorun ati ilepa re fun Olorun, o ye ki Korneliu gbo nipa ohun ti o gbodo se. O gbodo gbo awon isele nipa igbe aye Jesu Kristi. Fun apeere, ohun ti Jesu Kristi se nigba ti o wa laye ti o si nipa lori awon eniyan wa ninu (ese 36-38). A so fun nipa ise iranse agbelebu Jesu Kristi ku lori igi a sin in, o si jinde kuro ninu oku (ese 39-41). Kin lo tun ku? Pe Jesu Kristi je Onidajo aaye ati oku (ese 42). Elerii gbogbo awon woli pe ni Oruko Re ni gbogbo eni ti o gbagbo ninu re ri idariji gba (ese 43). Lotito imura tan Korneliu ati gbogbo awon ti o pejo nile re lati gba ohun gbogbo ti won setan lati gbo wu ni lori pupo (ese 33). Abayori eyi ni pe Olorun se iribomi Emi Mimo fun won, leyin eyi ni won se iribomi ti omi (ese 44-47). Awon iriri wonyi ni o ye ki gbogbo eni ti o gbagbo ninu Jesu ati ise irapada Re ni. Ore nje o ti gba Jesu Kristi gbo? Farabale lati gbo, ti o ba fe ki ogo ayeraye je tire, Kristi gbodo wa ninu re pelu igbagbo (Kolose 1:27). Se giri lati gbe igbese bayi Jesu Kristi n kan ilekun okan re (Ifihan 3:20). Pe e wole bayii.

Imoran Mi: Lati akoko yii lo, gbiyanju lati ni Bibeli kan ti o ko ba ni tele, maa ka a daradara bi o se n gbadura ki Olorun la oju emi re lati wo ohun iyanu ti o wa ninu Bibeli (Orin Dafidi 119:18). Darapo mo apejepo kan lati maa pejopo (Heberu 10:24-25). Je ki Oniwaasu re mo o ki o ba lee se iribomi ti omi ati ti Emi Mimo fun o (Marku 16:15-16, Ise Aposteli 10:44-48). Di eni ibukun titi lai.

Ti o ba fe ri wa: Pe awon nomba wonyi: 08032460619, 08033952947. Darapo pelu wa ni: No 9 Ebunoluwa Scott Close Araromi Layout, Beside Olieet Baptist High School. A maa n pade ni: Ojo Sunday 9.00 a.m Ojo Wednesday 5.30 p.m

ITORE-AANU, ADURA ATI AWE NIGBA GBOGBO KO TII TO

Lati Owo Edward O. Eruteya

G

bogbo eni ti o ba gbagbo ninu itore aanu, adura ati awe igba gbogbo gbodo ka ise iranse ti o wa ninu iwe pelebe yii. Bibeli ninu iwe Ise Aposteli 10:1-48 ni apeere kan fun wa (eniyan aye) nipa okunrin kan ati awon ara ile re ti won gbagbo ti won si n huwa rere. Pelu gbogbo ise rere re o si tun nilo lati gbo nipa ona igbala lati odo enikan ti o je iranse. Ki a so pato, o nilo lati gbo nipa Jesu Kristi ti o je Oluwa gbogbo eniyan, leyin naa o nilo lati ni iriri itebomi ti omi ati ti Emi Mimo. Iriri mejeeji yii se pataki lati siwaju itore aanu, adura ati awe nigba gbogbo fun eni yoowu ti o n wa ijoba Olorun. E jowo a ko fowo ro itore aanu, awe ati adura igba gbogbo seyin rara, a ko si so pe ko dara, sugbon bi won ti dara to, won ko to fun ijoba Olorun. Fi ara bale ka iwe Ise

Aposteli 10:1-48 ki o si fi okan re si ipa ogbon. Ohun ti akojopo iwe Ise Aposteli 10:1-48 n so ni pe o gbodo mo Jesu Kristi gege bi Oluwa ati Olugbala aye re; ki o si ni iriri itebomi Emi Mimo ati ti omi lai fi owo yepere mu itore aanu, awe ati adura igba gbogbo.

Ise Aposteli 10:1-48 (NKJE): 1Okunrin kan si wa ni Kesarea ti a n pe ni Korneliu,
balogun orun ti egbe omo-ogun ti a n pe ni ti Itali, 2Olufokansin, ati eniti o beru
Olorun tiletile re gbogbo, eni ti o n se itore-aanu pipo fun awon eniyan, ti o si n
gbadura sodo Olorun nigba gbogbo. 3Niwon wakati kesan ojo, o ri ninu iran kedere angeli
Olorun kan wole to o wa, o si wi fun un pe, Korneliu, 4Nigba ti o si tejumo on, ti eru
si ba a, o ni, kin ni Oluwa? O si wi fun un pe, Adura re ati ore-aanu re ti goke lo
iwaju Olorun fun iranti. 5Si ran eniyan nisinsinyi lo si Joppa, ki awon si pe Simoni wa,
eni ti apele re n je Peteru. 6O wo si ile enikan Simoni alawo, ti ile re wa leti okun:
Oun ni yoo so fun o bi iwo o ti se. 7Nigba ti angeli naa ti o ba Korneliu soro fi i sile
lo, o pe meji ninu awon iranse ile re, ati omo ogun olufokansin kan, ninu awon ti ima
duro ti i nigba gbogbo; 8Nigba ti o si ti royin ohun gbogbo fun won, o ran won lo si
Joppa. 9Ni ijo keji bi won ti n lo ni ona ajo won, ti won si sunmo ilu naa, Peteru gun
oke ile lo igbadura niwon wakati kefa ojo, 10Ebi si paa gidigidi, oun iba si jeun:
Sugbon nigba ti won n pese, o bo si ojuran. 11O si ri orun si, ohun elo kan si sokale bi
gogowu nla, ti a ti igun mererin sokale si ile, 12Ninu re li olorijori eranko elese
merin wa, ati ohun ti n rako li aye ati eye oju orun. 13Ohun kan si fo si i pe, Dide,
Peteru; maa pa ki o si maa je. 14Sugbon Peteru dahun pe, Agbedo, Oluwa; nitori emi ko je
ohun eewo ati alaimo kan ri. 15Ohun kan si tun fo sii leekeji pe, Ohun ti Olorun ba ti
wenu, iwo mase pe e li eewo mo 16Eyi si se ni erinmeta: loju kan naa a si gbe ohun elo
naa pada lo soke orun. 17Bi o si ti n go Peteru ninu ara re bi a ba ti mo iran ti oun ri
yii si, si wo o, awon okunrin ti a ran ti odo Korneliu wa de, won n beere ile Simoni,
won duro ni enu ona, 18Won nahun beere bi Simoni ti a n pe ni Peteru, wo nibe. 19Bi
Peteru si ti n ronu iran naa, Emi wi fun un pe, Wo o, awon okunrin meta n wa o. 20 Nje
dide, sokale ki o si ba won lo mase kominu ohunkohun: nitori emi li o ran won. 21Nigba
naa ni Peteru sokale to awon okunrin ti a ran si i lati odo Korneliu wa; o ni, Wo o emi
ni eni ti eyin n wa: ere idi re ti e fi wa? 22Won si wi pe, Korneliu balogun orun,
okunrin olooto, ati eniti o beru Olorun, ti o si ni oruko rere lodo gbogbo orile-ede
awon Ju, oun li a ti odo Olorun ko nipase angeli mimo, lati ranse pe o wa si ile re lati
gbo oro ni enu re. 23Nigba naa ni o pe won wole, o si fi won wo. Ni ijo keji o si dide,
o ba won lo, ninu awon arakunrin ni Joppa si baa lo. 24Nijo keji won si wo Kesarea,
Korneliu si ti n reti won, o si ti pe awon ibatan ati awon ore re timotimo jo. 25O si se
bi Peteru ti n wole, Korneliu pade re, o wole ni ese re, o si foribale fun un. 26Sugbon
Peteru gbe e dide, o ni, Dide, eniyan ni emi tikarami pelu. 27Bi o si ti n ba a soro, o
wole, o si ba eniyan pipo ti won pejo. 28O si wi fun won pe, Eyin mo bi o ti je eewo fun
eni ti i se Ju, lati ba eni ti se ara ile miiran kegbe tabi lati to o wa; sugbon Olorun
ti fi han mi pe, ki emi ki o mase pe enikeni ni eewe tabi alaimo. 29Nitori naa ni mo si
se wa ni aijiyan, bi a ti ranse pe mi: nje mo beere, nitori kin ni eyin se ranse pe mi?
30Korneliu si dahun pe, Ni ijerin mo n se adura wakati kesan ojo ni ile mi titi di akoko
yii, si wo o, okunrin kan alaso ala duro niwaju mi. 31O si wipe, Korneliu, a gbo adura
re, ore-aanu re si wa ni iranti niwaju Olorun. 32Nje ranse lo si Joppa, ki o si pe
Simoni wa, eni ti apele re je Peteru; o wo ni ile Simoni, alawo leti okun: nigba ti o ba

de, eni ti yoo soro fun o. 33Nitori naa ni mo si ranse si o lojukan naa iwo si seun ti o
fi wa. Gbogbo wa pe niwaju Olorun nisinsinyi, lati gbo ohun gbogbo ti a palase fun o
lati odo Olorun wa. 34Peteru si ya enu re, o si wipe, Nitooto mo woye pe Olorun kii se
oju saaju eniyan: 35Sugbon ni gbogbo orile-ede, eni ti o ba beru re, ti o si n sise
ododo, eni itewogba ni lodo re. 36Oro ti Olorun ran si awon omo Israeli, nigba ti o
waasu alafia nipa Jesu Kristi: (Oun ni Olorun ohun gbogbo) 37Eyin naa mo oro naa ti a
kede re yika gbogbo Judea, ti a bere si lati Galili wa, leyin baptismu ti Johannu waasu
re, 38A ni Jesu ti Nasareti, bi Olorun ti da Emi Mimo ati agbara lee lori: eniti o n
kiri se oore, n se dida ara gbogbo awon ti Esu si n pon loju; nitori Olorun wa pelu re.
39Awa si ni eleri gbogbo ohun ti o se, ni ile awon Ju, ati ni Jerusalemu; eniti won si
gbeko sori igi: 40Oun ni Olorun jinde ni ijo keta, o si fi ihan gbangba; 41Kii se fun
gbogbo eniyan, bikose fun awon eleri ti a ti owo Olorun yan tele, fun awa, ti a ba a je,
ti a si ba a mu leyin, igba ti o jinde kuro ninu oku 42O si pase fun wa lati waasu fun
awon eniyan, ati lati jeri pe, oun ni a ti owo Olorun yan se Onidajo aaye oun oku. 43Oun
ni gbogbo awon woli jeri si pe, nipa oruko Re ni ENIKENI TI O GBA A GBO yoo ri imukuro
ese gba. 44Bi Peteru si ti n so oro wonyi ni enu, Emi Mimo ba le gbogbo awon ti o gbo
oro naa. 45Enu si ya awon onigbagbo ti ikola, iye awon ti o ba Peteru wa, nitori ti a tu
ebun Emi Mimo sori awon Keferi pelu. 46Nitori won gbo, won n fo oniruuru ede, won si n
yin Olorun logo. Nigba naa ni Peteru dahun wipe, 47Enikeni ha le sofin omi, ki a maa
baptisi awon wonyi, ti won gba Emi Mimo bi awa? 48O si pase ki a baptisi won ni oruko
Jesu Kristi, nigba naa ni won be e ki o duro ni ijo melo kan.

Ore, tun iwe Ise Aposteli 10:1-48 ka lee kan sii lati lee so awon koko ti o se pataki ninu isele naa papo. O lee fe beere awon ibeere wonyi: Akoko, kin ni idi re ti a fi ran angeli si Korneliu nigba ti o ti n se ohun ti o mo pe o dara? (Wo ese 2 ati ese 30). Ekeji, kin ni idi re ti Korneliu fi ranse pe Simoni Peteru ki o wa lati Joppa? Kin wa ni eredi gbogbo isele yii? Se akiyesi oro ti a so